NIGERIA

# Iwadi Ọran

nipa

# Ile Dosunmu

Price—Sixpence

LAGOS
Printed and Published by the GOVERNMENT PRINTER,
1933

The Bancroft Library

University of California • Berkeley

WILLIAM AND BERTA BASCOM

COLLECTION

NIGERIA

# Iwadi Ọran nipa Ile Dosunmu.

Iwe yi ni Ọlọla Gomina Alaṣẹ tẹ sode fun gbogbo enia lati kiyesi.

Pẹlu aṣẹ Ọlọla Gomina,
A. C. BURNS,
*Adele Olori Akọwe Ijọbà.*

Ile Iṣẹ Olori Akọwe Ijọba,
Eko, 29th August, 1933.

---

Mo ti farabalẹ ka irohin Ọgbẹni Ward Price nipa bi a ti ṣe nyan Olori si ile Dosunmu, mo si fẹ kọ sọ ti ipo Ile na. Ọgbẹni Ward Price kọwe bayi ni apa kẹsan irohin rẹ̀ :—"Mo tanmọ pe bi Ijọba ba gbà, a o·ka Olori Ile na si (lọdọ Ijọba) bi enia ti o ndagbe lasan." Ohun ti a fa yọ yi ko si tabitabi pe a mu ẹnu kăn lati fi iṣoro ti yio ti inu rẹ jade han bi o ba jẹ otitọ. Ṣugbọn ko ri bẹ. Bi a ba yan Olori Ile na ni ọna ti Ijọba le fi ohun sĩ gẹgẹ bi ohun ti mo sọ lori rẹ ninu ọrọ mi ti ọjọ kẹsan oṣu May ti o kọja nigbati mo lọ ti mo si ṣi ipade wiwadi na, lẹhinna ti Ijọba ba si gbă, ninu ero temi oluwarẹ yio wa ni ipo kanna gẹgẹ bi Sir William McGregor ti ṣe fun Eshugbayi ni ọdun kejilelọgbọn ọhun ; ipo ti o daju pe o tẹ ile na lọrun fun ọpọlọpọ ọdun, eyini ni pe ki Ijọba to mu oju rẹ kuro ni ọdun 1920. Papa gidi bi a ba yan ẹniti o wọ̀ ti o le mu ki ija ti o wa ni ile na tan eyiti o dun ni pe o wa nisisiyi, ifẹ inu mi ni pe ki a gba oluwarẹ ti a ba yan bi Ọba (tabi bi Olowo bi awọn ara ilu ti npẽ) ti ile na, ṣugbọn gbigba bẹ na ko ni fũn ni agbara iṣelu, eyini ni pe ko ni jẹ ki Ọba nã da aṣẹ pa funrarẹ̀ ni ilu.

2. Mo ṣe akiyesi ninu apa kẹrinla irohin na pe :—

"Ni ipade ti awọn oniruru enia Ile na ṣe, ti awọn átọmọ-
"dọmọ awọn Ọba Adele, Akinṣemọyin, Ọṣunlokun
"(Ẹṣilokun), Ologun Kutere, Akitoye ati ti Dosunmu wa
"nibẹ pẹlu awọn obirin ṣaṣa diẹ, nwọn fi ohun ṣọkan pe
"gẹgẹ bi aṣa ati iṣẹdalẹ ibilẹ ki awọn ẹbi ile na má lọwọ
"ninu yiyan Olori ile wọn. Awọn Ijoye Onifila-funfun wa
"ninu ipadẹ yi nwọn si gba pe õtọ li eyi, awọn Lọya ti
"ọtun ati ti osi si gba bẹ̀ pẹlu."

Siwaju sĩ ninu apa kẹrindilogun irohin na mo kiyesi pe :—

"A ko ri ẹnikan lati damọran rara ninu gbogbo wiwadi na
"pe ẹnikẹni bikoṣe awọn Ijoye Ilu ati agbegbe rẹ̀ ni ọran
"yiyan Olori titun wa li ejika wọn,"

ati pe

"A le gbà pe iṣẹ awọn Ijoye Eko ati agbegbe rẹ̀ ni lati yan
"Olori Ile Dosunmu."

"Awọn ẹbi ile na pãpă gba pe yiyan Olori Ile na "ti ilu ni kiṣe ohun ti o kan wọn." (apa ọgọta).